# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 866 LAGOS SATURDAY MAY 4— MAY 10 KỌBO MEJI (2D) 1963


# Oyinbo Obinrin Ji Aso Taweli Gbe Ni Ile Ero

IKẸJA—Oyinbo German Obinrin kan ti o njẹ Ingril Jones ti o ngbe ile ponun marun ojumọ ni awọn Ọlọpa ti lọrun gẹgẹ lọ siwaju adajọ kotu pe o ji aṣọ tawẹli (towel) ti nwọn fi nmura gbe ninu ile-ero hotẹli ti o ngbe ni Federal Palace Hotel ni Okun.

Gẹgẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ro mọ Obinrin. Oyinbo na, nwọn ni lọjọ ti Obinrin na ti gunlẹ lati ilu rẹ ni o ti ngbe ile-ero na, o si nsan ponun marun ati sile marun ojojumọ fun sisun ti o nsun nibẹ. Gbogbo owo ti o san le ni igba ponnu ki o to kuro nibẹ.

Awọn ọlọpa ni lọjọ ti o kuro nibẹ ni awọn onile ero ni awọn fẹ aṣọ inura marun ku ninu iyara ti o ngbe. Were ni nwọn ti sọ fun awọn ọlọpa.

Nigbati awọn ọlọpa sure wa de idi ọkọ ofurufu ni Ikẹja, ti nwọn tu ẹru rẹ, gbogbo aṣọ tawẹli na ni nwọn ri.

Obinrin na bẹ adajọ, o ni ko jọwọ on si wọn ko mọ aṣọ on ni, ṣugbọn adajọ ni ki o lọ fi ponun mẹdogun tanran.

## Awon Omo Ilewe Ilesha Fake Kori

ILESHA -- Awọn ọmọ ile iwe giga kan ti nwọn npe ni Obokun High School fake kọri, nwọn binu fi ilewe na silẹ fun awọn olukọ wọn, nwọn ni nwọn ko kọ awọn ni iwe daradara to.

Ni ijeta ni nwọn ko awọn pali ti nwọn kọ ọrọ buruku si jade ti nwọn bẹrẹsi kọrin kiri wipe nwọn ko fẹ awọn tiṣa wọn mọ. nwọn ni ọrọ oṣelu ti awọn nṣe kiri ko jẹ ki wọn rojú raye gbọ ti awọn.

Nwọn ni eleyi ni ko jẹki awọn ṣe daradara ninu idanwo kan ti awọn ṣẹṣẹ ṣe.

## Oselu Churchill Fe Sinmi Ilu Sise



LONDON — Ari waya gba ni oru ana lati ọdọ akọwe oniwe irohin wa nilu Oyinbo wipe Ọlọla Winston Churchill, ẹni ọdun mejidinladọrun tiṣe Oṣelu pataki ni ilu Gẹsi fẹ sinmi ilu siṣe.

Alaye ti a gbọ nipa ọrọ na ni wipe Ọlọla Churchill paapa ni o kọ iwe pataki kan ranṣẹ si awọn ara adugbo ti nwọn na ndibo fun un wipe ki wọn yọnda on sile igbimọ awọn aṣofin.

Ọlọla Churchill ni on fẹ fi aye silẹ fun awọn ọdọmọkunrin ti wọn wa lẹhin on ki awọn na gbe ẹru ilu siṣe wọ diẹ. Ninu iwe na, ọlọla Churchill ni o dun on pupọ lati sọ wipe on ko fẹ ki wọn dibo fun on lọ si ile igbimo awọn asofin mọ.

A gbọ wipe o tọ ọgọta ọdun nisisiyi ti Ọlọla Churchill ti bẹrẹsi ba wọn ṣelu ni ilu oyinbo nisisiyi, o si jẹ aṣiwaju fun awọn oṣelu ilu Gẹsi na. Ọpọlọpọ igba ni o si ti ṣe Alakoso Ijọba ilu Gẹsi. Alagba Churchill jẹ ọlọgbọn pupọ sasa ni awọn Oyinbo ti o le ba a fi aga gba aga ninu awọn oṣelu ẹgbẹ rẹ.


**LAGOS RACE CLUB**

**June Meeting, 1963.**

SATURDAYS 25th MAY, 1st 8th and 15th JUNE, 1963.

Provisional Programme and Entry Forms can be obtained on application to the Secretary, P. O. Box 51, Lagos or at the Race Course Lagos.

Note—No Entry fees will be refunded after the draw has been made.

Entries close at noon on Monday 13th May, 1963.

No Cheque will be accepted.

C. H. B. MILLER
Hon. Secretary

## Abule Wu-kari Tu Ni-tori Owo Oran

GBOKO—Awon ara ib-... k.n ti awon po ni ... a ari leti ilu wa ... ... ti o tuka bama ba-na ... tor edeghartu po-nan ole ... (£9.025) ... l...ba loo...le Ariwa ni ki awon fi tanran ...run ... i_boro ti awon da sile nigba kan ninu oja ... won.

Gege bi ejo ti awon olopa ... won ... lori ... ro ... ighoro na lojo na ... ... ... won ... ... ... ye ... Ol... ... pelu si ... ... Oyinbo Ajele agbe ... be won. Ngbati awon olopa de ibe, nwon ... si nwon tuka, nwon ko jale.

Kaka ki won ma lo si ile won, igo ati kumo ni won beresi julu awon olopa yi, ti ope lopo ni-nu aw...n na si fi ara pa.

...won enia marundin-logorun ninu awon egbe olopa na lo da owo-or-an na san, sugbon nigb-ati awon olopa de abule na lati gba owo na lowo won, gbogbo ara abule na lo kanlu gbo, ti won wa ibi kan lo fara soko pamo is.

---

## Oniwayo Oyinbo Ti Lo Gbewa Lo-gba Ewon

EKO—Oyinbo kan ara ilu Rodesia isale Afrika ti oruko re nje Kenneth Neil Straford, eni odun merindilogbon, ni adajo Kotu awon Olopa so se-won odun merin ati abo ni ijeta fun esun ole ati jibiti ti o gi e opolopo awon enia ni ilu yi.

Ejo ti awon Olopa ba Oyinbo orijibiti na ro ni pe ki o le ri bi se iwa ji biti re, o lo ba opolopo awon onisowo, o ni oga ise ojon ni ile ise awon Oyinbo kan ti oruko won nje Dorma Long Com-pany.

(Wo iyoku ni oju ewe Kejo)




The load is heavy, the ground difficult, the engine is working at full power and yet the driver has perfect control. The light Mercedes-Benz re-circulating ball steering is precise to a fraction of an inch. Exact manoeuvering, safe use of marginal space, absolute track steadiness and excellent lock are features of this steering which is just one of the many advantages that all Mercedes-Benz trucks and buses have in common.

**Precision to a fraction of an inch**



MERCEDES-BENZ

Available at:

**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS (EB) IBADAN: KANO: KADUNA: JOS: PORT HARCOURT: ABA.

Sub—Distributors:

**ARMELS TRANSPORT LTD.**

BENIN CITY. ONITSHA. ABA.

## Awon Iwe Asiko:

# Fifi Owo Pamo Si Banki (2)

Nipa Iwe Alufa ATILADE
(o bẹrẹ lati ọsẹ ti o kọja)

### Iwofa

Ọmọ yi le sin fun ọdun mẹwa tabi jubẹ lọ. Ni ọjọ ti elowo yio ba gba owo yi pada, poun marun rẹ yio pe sanmusanmu. Gẹgẹbi ti ẹru rira ni eleyi na mu iwa ika ati irẹ ọmọnikeji ẹni jẹ dani. Nitori eyi ni awọn ijọba ilu ti o laju ṣofin lodi si iwọfa yiya.

Ọna ti o rọrun julọ, ti o si fi ọkan enia balẹ ni lati fi owo si Bank, ile ifi owo pamọ si. Eyi yi ni ọna ti a nlo ni gbogbo ilu ti o laju ninu aiye.

## Lati owo AKOWE

### Owo Banki

Inu wa dun pe a ni iru awọn ile fi owo pamọ si bayi ni ilẹ wa. Fun apere, a ni National Bank ti Nigeria, Bank of West Africa, Post Office, African Continental Bank, Barclay's Bank, Bank of America ati awọn miran nibiti a gbe le fi owo wa pamọ si pẹlu ifọkanbalẹ. Ọpọlọpọ enia gba pe o ṣoro pupọ lati fi owo si Bank nigbati o jẹ pe o rọrun pupọ.

Bi o ba fẹ fi owo pamọ si Bank, wọ yio mu owo na lọ si ọdọ Akọwe ni Bank. On yio fun ọ ni iwe penpe kan. A ti fi aye silẹ fun ọ lori iwe yi ibiti iwọ yio kọ orukọ rẹ, ibiti o ngbe ati ọjọ oṣu ati ọdun na si.

### Iwe Owo

Lẹhin igbati o ba ti kọ awọn nkan wọnyi yi silẹ tan iwọ yio wa kọ orukọ rẹ si isalẹ iwe na ni ọna ti iwọ yo ma fi kọ orukọ ni igba gbogbo; bi ẹlomiran yio ba wa ti yio kọ orukọ rẹ lati gba owo rẹ, ki nwọn ba le fi kikọ orukọ na we ara wọn, bi kikọ orukọ na ba ba tirẹ mu. Ẹhin eyi, Akọwe Bank yio mu iwe pokiti kan jade yio si kọ orukọ rẹ sinu iwe na. Iwọ yio fun u ni iye owo ti o fẹ fi pamọ. Yio kọ iye owo ti o fe fi pamọ, yio si fi ontẹ Bank tẹ ẹ, yio si kọ orukọ ara rẹ ati oṣu sii.

Ni ipari, yio gbe iwe nla Bank, yio si kọ namba ti iwe rẹ, orukọ rẹ ati iye ti o mu wa si oju iwe titun ti yio wa fun ilo orukọ rẹ nikan.

(iyoku di ọsẹ ti mbọ)

# Olopa Kan Fi Igba Ponun Tanran

YABA- Adajọ kotu awọn ọlọpa Yaba, Ọgbẹni F.A.S. Ogunmuyiwa ni ki ọlọpa Ijọba Apapọṣe ilẹ Nigeria kan ti oruko rẹ nje Hamzat Raji, ẹni ọdun mọkanlelogoji lọ fi igba pọnun (£200) tanran fun pọnun meji owo-riba ti o gba, tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu mejila.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa ọrbẹ rẹ ba a ro ni wipe nigbakan ẹdaran ọlọpa yi mu derabu Cnimcte kan ti o njẹ Paul Aitekhome mọto ti o nwa.

Nwọn ni dipo ki o fi ẹjọ ẹsun rẹ si Kotu nṣe ni o lọ gba pọnun meji lọwọ enia arufin yi ti o njẹ Emes Atakei, ti o ba si pa ọrọ na mọlẹ bamubamu.

Adajọ ti o da ẹjọ na ni on ko le fi oju anu wo ọdaran ọlọpa na nitoripe awọn ti se ikilọ fun awọn Ọlọpa yi wipe ki nwọn maṣe ṣe wọn lọna ti o tọ ki nwọn ye gba owo-ẹhin mọ.

# Bi Ere Sakara Se Bere (2)

Akigbemaru

Gẹgẹbi alaye ti mo ṣe fun yin ninu iwe itan mi nipa BI ERE SAKARA ṢE BẸRẸ ni ọdọ awa Yoruba ni iwọn nkan bi ọdun metadinlogoji sẹhin ninu iwe Eleti-Ọfẹ ti ọse ti o kọja; mo ni igba aiye atijọ aṣeyẹ igbeyawo ni awon Yoruba ti o ba jẹ Imale ma nṣe pẹlu ariwo. Nwọn ki parwo nibi oku Imale rara, ko dabi ti ọjọ ode oni ti ilu ati ijo ngbejika nibi oku Imale nibikibi ni ilẹ Yoruba.

Mo ni ẹnikẹni ti ohun rẹ ba dun, ti o ba mọ MOLO ta daradara, ti o si mo eni ki ni oriki daradara ni ibi faaji ni awọn alugba sakara yi ma fi nṣe olori; olona si ni lati jẹ olohun iyọ

### Ote Eko

Ni asiko ti ere awọn alugba sakara yi gbokidan ni ilu Eko ni asiko ọtẹ ilu. Oloye Ọbanikoro igbana Adamu Akẹju) jẹ ẹnikan ti o gba awọn ara Ilọrin pupọ si agbala rẹ, o si fẹ ọkan ninu ọmọ Ilọrin ti o jẹ gbajumọ ti oruko rẹ njẹ BELAWU. Bi awọn al gbe ara Ilọrin ti o wa lojude Ọbanikoro ba jeun yo tan, nwọn a gbe igba ati Molo jade nwọn a ma kọrin ki Oloye Ọbanikoro.

Mo niran ọkan ninu oriki ti nwọn ma aki Oloye Ọbanikoro na ni igbaiye rẹ, nwọn a ma ki i bayi "ARIJẸ ninu madaru, ọkọ BELAWU" Oda mi loju pupọ wipe lode awọn ara Ilọrin ti nwọn nwa ṣere sakara fun Oloye Ọbanikoro, Adamu Akẹju, yi ni Ologbe Abibu Oluwa ti fi eti kọ bi nwọn ti nta molo awọn Hausa ati ọna ti awọn ngba ṣe ere igba lila.

Gẹgẹbi mo ti ṣe akiyesi Ologbe Abibu nigba aiye rẹ, o jẹ ẹniti oloju ọna,

(Wo yoku loju ewe kẹfa)



Ologbe Abibu Olatunji Oluwa

ORUN RE O

# ELETI-OFE

A NJUWỌN KOSE WI ...

EDITORIAL OFFICE & WORKS
28, Kosọkọ Street, Lagos.
P. O. Box 467
CABLE & TELEGRAM
"ELETI-OFE" LAGOS
Phone 23370
VOL XIV. No 1867 SATURDAY MAY 4 MAY 10 1963.


# Odun Ileya

Nigbati ẹ ba nka ọrọ Olotu wa yi gbogbo ẹnyin Imale ti ẹ nṣe ọdun Ileya yio ti pa ẹran agbo yin lati fi ṣe iię fun Ọlọrun ti o da yin tọmọ tọmọ lati tun ri ibẹrẹ ọdun titun miran; awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ ki nyin, ẹ ku ọdun, ẹ si ku iyedun.

Ṣugbọn a fẹ ki ẹ mọ itan pataki kan lati inu iwe Alukurani yin ti o fa ọrọ a npa ẹran lati fi ru ẹbọ si Ọlọrun lọdọdun yi wa. A gbọ wipe ọrọ bẹrẹ lori Anabi Ibrahim ti Ọlọrun ni ki o fi Isimẹli, ọmọ kan na ti o ni lati e lọrun rubọ fun on.

Gbogbo a ọ Imale ti o ba ka iwe Alukurani wọn daradara lori itan yi yio ri ọkọ nla lori IFARADA ... ọrọ Anabi Ibrahim pẹlu ọmọ rẹ kọ wa.

## Odun Ifarada

Gẹgẹbi awa ti ri ọrọ itan na, nkan ti o kọ wa pọ nipa igbesi aiye awa ẹda ọmọ Adamọ, o kọ ni ọna ti ti a le fi nkan ti o jọwalọju pupọ tọrẹ fun ẹnikeji wa.

Nwọn ni sara ni ẹbọ Imale; ngbọ iwọ Iya Adini ati Baba Adinni iọna ọja. tara yin nikan kọ ni ẹ ndu? Ẹ jẹ ka fi igbakan ro tire tọmọ ọlọmọ ti o nṣiṣẹ lọdọ yin lati mu inu rẹ dun ninu ọdun. A ni ki alamọri ti yin ati ti ọmọ yin ṣa ti dara.

Ki a ti ibi iṣana kiyesi ẹtu, ẹniti ko ba ha yin ni ẹran, ẹnyin na ni ha a? Sibẹsibẹ nwọn ti fi ọrọ ẹran Ọdun Ileya pipa yẹ yin wipe fun itọrẹ awọn talaka ti ko ri nkan je to ti yin ni ki ẹ ma fi wọn ṣe lanu.

Ọrọ re o, Iya Adinni Isalẹ Ọja ati Baba Adinni Oke Ọja. Ẹ ku ewu ọdun, ẹ si ku iyedun. Ọlọrun ko ṣe ọdun na ni abo ọdun fun gbogbo wa-

# Ominira Pajawiri..

Awọn agbalagba Yoruba ni igi ganganran ma gun mi loju, okere ri a ti nsọ o iyẹn ni ọrọ Ominira tun tun ti Alakoso Ijọba Apapọṣe ilẹ Nigeria, Ọlọla Tafawa Balewa, ṣe ti ede wipe awọn fẹ fun wa ni nkan oṣu mẹfa si igbati a wa yi. REPUBLIC ni orukọ ti awọn Oloyinbo npe eto OMINIRA-ALAILOBA na.

Ẹru jinjin mba awa onirohin Eleti-Ọfẹ nigbati a ko mọ iru eto ti nwọn ṣe sifi ti Ominira Pajawiri na, eleyi ni ko le jẹki a ki yin ku ipalẹmọ ti ominira na. Ni ona kinni . yẹ ki awọn alamajutu Ijọba wa fi oju iwe ... wa ki a le tete mọ iru oko-ẹru ti a nlọ.

A gbọ wipe a ni lati pa ipo Gomina rẹ ati pe a ... ni rababa fun Ọba kan mọ. Ẹ jọwọ, ẹ la iru anfani ti o be wa ninu ominira-alailọba yi fun wa, ki a mọ ye ti ominira-pajawiri rara. Ọjọ na sun mọle tan.

# Iwe Si Olotu

## ENIA KIKA TUN DE !

Olotu a dupẹ lọwọ yin fun wahala yin ti ẹ nse lori ẹrilẹ ede yi nigba gbogbo, paapa lori awọn enia ti e tun tete ti yan si wa leti wipe nwọn fẹ ka.

Ẹnyin na ti sọ otitọ ọrọ fun wa wipe abọ ọrọ ni a nsọ fun ọmọluwabi, o si yẹ ki awọn enia wa, awọn Yoruba eleti kunkun gbọ ikilọ yin, ki nwọn jẹki nwọn ka wọn tọmọtọmọ.

Enia kika ko nṣe fun eto owo-ori bikoṣe fun lati mọ eto ti nwọn yio ṣe fun idagbasoke ilu ati inawo ti awọn yio ṣe nipa bi a ti npọ nilu si.

Ẹ ma jẹki nwọn ko iyan awa Yoruba kere o, ti ẹ jẹki nwọn ka gbogbo wa.

Emi ni,

Apapa Ade Idowu

## Oro Na Ku Die Nitoto

Mo gba fun yin, Olotu fun ọrọ yin ti ẹ sọ sinu iwe irohin Eleti – Ọfẹ ni ọsẹ ti o kọja wipe egungun ti a ba fi ha aja lọrun ni ọrọ Oloye Okotiẹ-Eboh ti nwọn fẹsu kan ni ile Igbimọ Apapọṣe l'Eko pe o mba awọn oniṣowo onibata kan ṣe iṣẹ owo pọ. Ọlọla Tafawa Balewa ni ki nwọn ju u silẹ, awọn minisita on le ṣe owo.

Nitotọ, o yẹ ki Ọlọla Tafawa Balewa ti a pe ni baba gbogbo wa ṣe ikilọ fun awọn Minisita rẹ ki nwọn ye ba wa du owo ṣe kakiri ni ariu ilu nigbati awọn ba nṣe alamojuto iṣẹ Ijọba.

Ẹ ṣe pupọ fun aye ti ẹ gba mi, ọkọ Ọba ko ri ṣa yin lẹṣẹ.

Emi ni,

Ebute Mẹtta D. Johnson



Ọlọla John Hunt, Aṣoju awọn ọmọ Gẹsi ti awọn gun oke kan ti o ga julọ ni aiye nigba kan ti nwọn npe ni Mount Everest ni o nfi ẹbun medali ti awọn ẹgbẹ ọjọgbọn ilu Gẹsi fun han iyawo rẹ lori iṣẹ pataki kan ti o ṣe fun awọn ẹgbẹ na.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## (Lati Owo Ayiluka)

### Alhaji Ibo

Inu mi dun popọ wipe ni igbesi aiye mi mo ri ara ilu Ibo kinni ti o kọ lọ si Mẹka lati ṣe ẹsin Imale. Ẹnyin ọkawe mi, orukọ Ọgbeni wa na ni Seidi Ibrahim Niass Nwagui, ara Afikpo ni ai Ipinlẹ Ila Orun leti Ẹnugu.

Mo gbọ wipe Seidi Nwagui ti o ti gunlẹ si Mẹka ni ọsẹ yi ti ṣe waasi fun awọn ara ilu re ki o kuro nile wipe ẹran agbo dun jẹ ju ti ẹran ẹlẹdẹ ati ti ẹgi lọ, ti enia ba si pa agbo tan, ti o nfi awọ re kirun ni wakati ni wakati pẹlu tẹsuba lọwọ. Oluwa-rẹ yio ma ri laada, inu rẹ yio ma rọ, ko ni fada yanju ọrọ ai abulo wọn mọ.

### Rekia Aba

Mo gbọ wipe Alhaji Nwagui ti fi waasi rẹ yi awọn Ibo bi ẹgbẹdogun enia pada si ẹsin Imale, iyẹn ni wipe laipẹ yi a o ma ri ọpọlọpọ 'awọn Ibo ti awọn yio ma yi orukọ wọn pada, ti nwọn vio ma jẹ Wahabi Okolo, Yesufu Nwosu, Jimọ Ejiofor, Rekia Auosike, Saiamọtu Njoku ati orukọ bẹebẹ ti nwọn njẹ ni ilu Mẹka ati Mẹdina. O ko, bi aṣa awọn Ijẹbu, aiye nlọ a ntọ, ṣugbọn o yẹ ki gbogbo awọn Imale Ibo ma ke awọn ọmọ wọn jape lọjọ mẹjọ mẹjọ ẹ-gbẹn ko gbẹdọ si ọti "MAYAN" ti ẹ npe ni ẹmu aibọ aitoripe ẹsin Imale ko fẹ ọti mimu rara.

### Oba Kano

Mo gbọ wipe ogunlọgọ enia ni Ọlọla Ahmadu Bello, Sardanna Sokoto mu lọ si irin ajo Mẹka lọdun ai, a fi ẹrẹ rẹ atijọ, Ọba Kano ti ana, Alhaji Muhammadu Sanusi, ti nwọn wa kuro nilu lọ si Azare ni igberiko kan ni Bauchi ti Ọlọla Ahmadu kọ, ti ko mu lọ si irin ajo ilu Ọlọrun nitori Anabi.

Mo gbọ wipe ki awọn ọkọ Mẹka to ka'le nilẹ ni Ọba Kano ana yi ti fi iwe-ẹbẹ ranṣẹ si Ijọba Ipinlẹ Ariwa wipe on fi Allah bẹ awọn alamojuto Ijọba wọn ki nwọn fun on ati akọbi ọmọ on laye lati lọ si Mẹka ti ọdun yi, on fẹ sin Ọlọrun on si ni ọna ti o dara. Nwọn ni a ki ma gbọ gbonmọ gbọnmọ ni ile agba ni ẹmeji, nwọn ni ibikibi ni Ọba ana yi le sin Ọlọrun re ko ba ṣe inu ibamọ ni.

Emi Ayiluka gbọ wipe Ọba ana na ti ogoji ọṣẹ pẹlu ogun ogunfe fun Ọdun Ileya yi nibi ahamọ re wa. Nwọn ṣenu foro fun mi wipe ọmọ rẹ ti nwọ duro ni ahamọ l'Eko ti lọ ba a ni Azare. nwọn yio ṣe ọdun pọ ni. Mo ki ọba na, o ku agba.

### Pasan Tuntun

Ẹnyin ọkawe mi, ṣe ẹ ti gbọ nipa ọrọ ẹgba pasan tuntun ti a fẹ ra funra wa ni ilu Nigeria ni aipẹ yi ? Ṣe ọpa wahala ile ni o ma nwa ẹniti o ba fẹ ni o nfi ọwọ ara re fa a.

O ku oṣu mẹfa nitisiyi, ilu awa yio gba OMINIRA ALAILỌBA; a fẹ D'OBE LADATAN, a fẹ kenboki. Ominira-alailọba na ni awọn ape ni REPUBLIC, iyen ni wipe a ko ni fori balẹ fun ọba kan kan mọ, ko ni ṣe Ọba enia-dudu tabi alawọ funfun a fi Gomina Ọlọla papa a kan sile, ṣugbọn a lati ni BALE, ẹniti a o fi jẹ Balẹ na a ... mọ.

### Iyawo Arede

Gbogbo ... na ku ... mọfi loni ... alaye ti Ọlọla Tafawa Balewa ṣe ni o Igbimọ ... fun awọn ... ti a ran lọ ... joko ipade awọn Igbimọ ... nina ọsẹ yi. Ṣe ẹnyin na mọ wipe ọdọmọkunrin ti o ba fẹ te a gbe alejo ọmọge ni iyawo arede pajawiri.

A ko ti ṣe eto ominira-alailọba yi, ki a gbe s'waju awọn ara ilu; a fẹran akan pajawiri nilẹ wa yi pupọ. Ana a gbọ Olotu Ijọba pajawiri, oni a yan Adele Minisita alamojuto pajawiri, hẹta a lọ si Kotu pajawiri, ni ọla ọjọre yi ni a tun fẹ bọ sinu Ominira-alailọba ONIPAJAWIRI. Gbogbo rẹ d'ọwọ rẹ, Ọlọla Tafawa Balewa, Ọrọ pajawiri su wa nilẹ yi o.

CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENT:
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, Balogun Street, Lagos.

# Bi Ere Sakara Se Bere

( o bere lati oju ewe keta )

ori re s ro si ati tete fi okan s i kan diradura. Oto ni ona ti awon ara Ilorin ... ni ava Yoi- ... isale ... nlu ...

Mo se akiyesi wipe ilu kan kekere ti awon Hausa ma npe ni "kanango" ni awon Tapa ati Hausa ma nlu si ere na ti faaji ibe ba ko s w r n lori. Ni odo awa Yoru- isale odo-Oya ... igba as ilu sakara na ... IFE-ORUNSA kun nito- ripe duoja ... "kanango" won, sisa enia no ... si mo o lu.

## Igba Ademu

Bi e ba se akiyesi nkan eroja ti a awon onisaka- ra ode oni nlo, e o ri wipe igba-ademu ko po ninn won tobe mo Igba- ademu yi je nkan pata- ki ninu nkan eroja awon onilu sakara ti o je wipe awon eni akan ma nri bi enia bayi: "A BI ORI DAN BI IGBA- SAKARA"

Ngbati ... ijo sakara ti mo ... itan re yi bere si jo ni akobere, awon ilu ti ... a bi eniti o gba orisa Sango ni awon Imale ilu Eko ati Abeokuta. Gbe gbo awon sanmori ti nwon ba fe gbe iyawo ni ... ti nwon ko ba pe ... sakara sibe agbo ibe ko n -kun soso fun awon omo e ati awon odomokunrin ti nwon nle se gbajumo.

## Obinrin Dipomu

Mo nran ... orin sakara kan ti awon elere sakara ko ni ilu Abeokuta lori awon obinrin akoko ti npe ni DIPOMU ni ilu awon Egba bayi nwon ko orin na ni iwon nkan bi odun metalelogbon (1930).

"Ademola so won d'eru,
O so lebeli mo won lorun,
Boyisi ti ko fobinrin,
E je lo s'Ako"

Lehin eyi awon onisa- kara ilu Egba tun ko orin miran ti ko mu ebu ilu wo fun awon agan obinr-

bavi:

"Bi a ba ra eru,
Eru a sa
Bi a va ... ,
A re 'lu re;
Fun mi ni temi
Fun mi temi,
Ki ... hrohun gbejo"

Ni adugbo ti awon oni- sakara gbe wa pupo ni Abeokuta ... Ago-Owu, Ago Ika ati Oke Ona mo Mokola, ... n w e n ko ... be po ni Ako mo

Ijemo ati Ibara ni adu- gbo awon Ibarapa. Ilu gangan ati aponran ni awon orio Ijaiye mo owo re ko si si eniti o le ba won nila ijo aponran na.

## Orin Owbon

Gbogbo orin ti Ologbe Abibu ko nigba aiye re lo mu ogbon ati lakaiye lowo. Tani le so wipe eyi ti o ko fi ki Oloye kan ninu awon omo Eko ti nwon npe ni Sehinde Oshodi ti o se ba- yi ko mu ogbon lowo:

"Aderibigbe Olasehinde!
Agba ko si ilu baje,
Bale ile ku ile dahoro,
Ijakunmo ki rin osan,
Eni a bi re k rin ru,
Eni se rere ko mura sire,
Eni nse ka ko mura sika,
Ati ere ati ika,
Ikan ko ni gbe,
Aiye lokun, enia losa."

Beni, enyin ara mi, aiye lokun, enia losa; ore orin Ologbe Abibu ti o mu lakaiye lowo ti o ko po pupo ju sugbon ma duro nibiu.

Bayi ni ERE SAKARA ŞE BERE lodo awon Yo- ruba Imale wa ki o to di nkan ti gbogbo awon kan nfi se owo-şişe ni awo rekodu lode oni, ti nwon si mbu ara won lebu ke- bu. Abibu Oluwa orin re!


JAPANESE BICYCLES



• STRONG
• SPEEDY
• SMART

TODAY JAPANESE BICYCLES COVER THE WHOLE WORLD

For import informations apply to:

JAPAN BICYCLE TRADE CENTER
P. O. Box 4117, BEIRUT LEBANON
CABLE EXBIKE BEIRUT

# Textile Tips On Nigerian Fashions British Corporation Makes A Move

LONDON — The British National Wool Textile Corporation has been sounding the views of a group of Nigerians studying in Britian, on the subject: which kind of dress do Nigerians prefer, traditional or Western ?

The questions were put in preparation for the launching of the Corporation's campaign in October to promote the sales of British wool cloth and knitting yarns in Nigeria. The campaign will open with fashion parades in Lagos and other principal cities.

A panel of Nigerians, led by Mr. Akando Dahunsi, Chief Education Officer of Lagos, who is on a practical attachment to the City of Hull, put its views to the Corporation at a special lunchion in Bradford-centre of Britains woolen industry.

To the question, "What should be the proportion of traditional costumes to Western dress? Mr. Dahunsi replied: "People in the cities are inclining more to wearing Western dress and this is having an iufluence in the village. Let us see a good choice of Western dress, which is smart and comfortab e, alongside on equal num— ber of traditional gar ments.

Six Nigerian students-all studying in the Bradford area-who also served on the panel, had differnt views.

Said Mr. Dipo Ogunsulire from Ondo, an Economics student at Bradford Instit te of Education National costume is still most popular in Northern Nigeria and the country districts, It would be better to include 70-80o/o of these garments in your parade."

Putting a woman's point of view, Miss Yemi Akinsete, daughter of Chief Akinsete of Ondo, said : "We like traditional dress but we also like Western dress.

I am sure Nigerian woman would like to see African and Western fashions in equal numbers at this parades"

Other members of the panel were: Miss Celestina Enene Briggs of Enugu;; Mr. Yemi Ladipo of Ibadan and Mr Phillip Abiodun Oneneyin of Ondo-all studying at Bradfor Technical College and Mr. Sunday Babatunde Onadeko a Lagos jornalist

Before the discussion, the panel visited a yorkshire woollen mill and several orders being prepared for wellknown firms in Nigeria.

---

## African Parliamentarians In Britain

LONDON Three West African Parliamentarians-from Nigeria, Sirerra Leoand Gambia-will hear all aspects of Parliamentary democracy discussed by by experts during a month's course as guests of the General Council of the Commonwealth Parliamentary Association and af the British branch of the CPA.

Joining the course at Westminster from today until 29th May are Mr. F.U Mbakogu, M. P. Parliamentry Secretary to the Nigerian Federal Minister of Economic Development, the Hon. Waziri Ibrahim, M.P. the Deputy Speaker of the Sierra Leone House of Representatives, Mr J. E H. Tucker; and the Speaker of the Gambia House of Representatives, the Hon. A. S. Jack.

## Two Nigerians Join Crop Protection Course in Britain

LONDON — Three West Africans-two Nigerians and one Ghananian-are among 16 overseas specialists who have just begun a six months' course on crop protection in Britain.

The Nigerians taking the course at Fisons Pect Gontrol Ltd., under Nigeria/U. K. technical assistance arrangements, are Daniel Abi Bolarin of the Institute for Agricultural Research, Ahmadu Bello University, and Fidelis Chukwunwike Ogbogu, Assistance Agricultural Superintendent, Ministr of Agriculture, Eastern Nigeria.

The group will spend most of their time at the Company's research station near Cambriage. During the next six months they will make a detailed survey of the present principles and methods in the whole field of crop protection within Britain and in overseas countries.

The subjects covered range from pesticidal research spraying machinery and safety precautions to weed control of rodents and insectpests; and the course also includes a comprehensive programme of practical visits and attachment to Government research stations, agricultural shows and leading manufacturers of agricultural machinery and pesticides.

## Nigerian Sailors Train in Britain

LONDON—To gain technical knowledge vital for the future expansion of the Royal Nigerian Navy, two young Nigerian sailors are now on a nine-months coures at the British naval base at Portsmouth.

They are Christopher C. Okeke, of Uke, and E U. Egbuleebu, of Aba, and at the Royal Navy's electrical training establishment, H. M. S. 'Collingwood," they are learining to use and maintain equipment on every type of ship from light patrol craft to battleships and submarines.

Okeke and Egbuleebu joined the Royal Nigerian Navy together on the same day; they trainined together, served together aboard H. M. N. S. "Nigeria," and on H M.N.S 'Enugu.' Their present course, which they are taking with sailors from the Royal Navy and other Commonwealth navies, will fit them to become Petty Officers in the Electrical Branch.

## Nigeria's New Liner

LONDON- Nigeria's new cargo liner, the "Ahmadu Bello," has carried out successful sea trials off Tyneside, north-east England.

She is a sister ship to the "Nnamdi Azikiwe' and both have been built for the Nigerian National Shipping line Ltd. by Swan Hunter and Wigham Richardson. But there is one difference-the second ship has been equipped to carry 12 passengers as well as refrigerated cargo, vegetable oil, latex and glycerine.

Following her successful trials the Ahmadu 'Bello' is due to leave the Tyne for Middlesbrough where he will load a part cargo of steel. After a few days stop in London she will continue her maiden voyage to West African ports,

## Oniwayo Oyinbo Ti Lo Gbewa Logba Ewon

Ọdaran Oyinbo yi ti wayo yi lati fi gba fọnmọto, eyo kọlọ kan, ere Redio Alayoran kan ati awọn nkan miran ni sọbu. Awọn Ọlọpa ni o fi ọgbẹnjẹnis ti Oyinbo onijibiti yi lọ ni wọye nigbati o ti gunlẹ si ilẹ yi.

Nwọn tun ṣe alaye fun adajọ ti o nṣe ẹjọ na wipe gbogbo ilu ti Oyinbo Oniwayo yi ba lọ ni o nlu wọn ni jibiti on paapa tile jẹwọ iwa ipa ati iwa ibi ti no ti hu kakiri agbaiye. Adajọ ni ti o ba ti lọ igba rẹ tan ninu ọgba ẹwọn ni ki awọn lọlọpa wa Oyinbo na kuro nilu patapata.

## Loya Oloye Enahoro Tun Gbe'jẹ Dide

LONDON — Lọya Oloye Anthony Enahoro ti awọn adajọ kan ni ilu Oyinbo ti paṣẹ fun wipe ki awọn da pada si Nigeria lati wa jẹ ẹjọ ọtẹ ti nwọn fẹ ba a ro ti fi iwe awitẹlẹ si ile igbẹjọ awọn ogunna gbongbo ilu Oyinbo pe on tun fẹ ki nwọn tun gbe ẹjọ Oloye Enahoro na yẹwo.

Ọgbẹni Dudley Smith tiṣe ọmọ ile Igbimọ aṣofin ni ilu Gẹsi ni awọn ti fun lọya Enaharo na laye lati wa sọ tẹnu rẹ ni waju awọn ọjọgbọn na.

A gbọ irohin pe lọya Enahoro fẹ ko iwe pataki kan si iwaju awon ọjọgbọn ile aṣofin na lọjọ ti o ba foju kan wọn ninu ọsẹ ti a fẹ bọ si yi.



Aworan yi ni igbati awọn elere bọlu afẹse gba ti ilu Liverpool fi nga gba'ga pẹlu awọn elere Fulham; irohin ko te afojuba ni ọrọ ere wọn na ti nwọn ṣe ni aipẹ yi Ẹniti o fẹ mu bọlu ti nwọn gba wọle ni o ṣubu silẹ yi.

## Awon Ole Sa Olopa Lada Ni Pota

PORT-HARCORT—Awọn ogbologbo ọlọṣa ṣa awọn ọlọpa ati ọga wọn ladi ni inu igbo kan ni Diobu ni oru ijẹta nigbati nwọn nfẹ lọ ko ile onile; gbogbo awọn ọlọpa ti nwọn gba ọgbẹ na ni nwọn ti ko wa si ile awọn alaisan nibi.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ lọdọ akọwe onirohin wa ọga ọlọpa agba ni o yan awọn enia kan ninu awọn ọlọpa ti nwọn wa labẹ rẹ wipe ki nwọn lọ ba si inu igbo leti odo kan ti nwọn npe ni Ntanwagba, ibusọ mile meji si Diobu, nitoripe awọn gbọ pe nibẹ ni awọn ọlọṣa gbe nsa pamọ si.

Nigbati o di ọganjọ oru ni awọn ọlọpa nibiti nwọn gbe sa pamọ si, ri ọkunrin kan ti o ngun kẹkẹ ologere lọ, ọkan ninu awọn ọlọpa na ba daa duro. O bi lere nibo ni o nlọ ati pe nibo ni o ti mbọ.

Nibiti awọn mejeji ti nsọrọ yi lọwọ ni awọn ọlọpa yoku sare jade ninu igbo lati gbọ nkan ti baba onikẹkẹ no nsọ.

Nigbati Ọgbẹni na ri wipe ilẹ ti yi ọu ka ni o ba kesi awọn ara rẹ ti nwọn ti fara soko ninu igbo wipe ki nwọn gba on.

Lọsẹ kanna, awọn bienia mẹdọgbọn ti nwọn sau bantẹ-dudu ti sare jude pẹlu ada ati kunmọ lọwọ wọn; nwọn lu kisa si awọn ọlọpa na lara.


**Plushes, Velvet, Velveteen, Damask & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunnowo Brothers**

65, Massey Street, (Faji Market)
LAGOS, NIGERIA.

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos, Box 467 Phone 23370 Editor, (Olomu ...) Onatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos.